# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No 764 FRIDAY AUGUST 7 1964 (2D)


## Ẹgbẹ Afẹnifẹre Ward C. Yan Awọn Oloye Titun

EKO :— N. Ọjọ 'Ru ti nṣe ọjọ karun oṣu yi ni awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Ward C L'Eko yan awọn Oloye titun fun Ọdun 1964 si Ọdun 1965, awọn ọmọ ẹgbẹ Afẹnifẹre ti Ward C na si jẹ ẹka marun ti nwọn si papọ jẹ ẹkan ṣoṣo ni agbegbe na.

Ki Ipade lati yan awọn Oloye titun na to bẹrẹ ni Ọ bẹni Agbalaiya kọ fi Adura ṣi ipade na. Lẹhin na ni awọn ọmọ ẹgbẹ na fi awọn ẹniti yio ṣe eto lati yan awọn Oloye na han ninu wọn ni Ọgbẹni Gan yu Daodu ọkan ninu awọn ọmọ ile Igbimọ ti Ijọba Ibilẹ ilu Eko ati Ọgbẹni M. Mugaji,

Eyi ni orukọ awọn oloye na ati ipo wọn Ọgbẹni S. O. Ajayi alaga, Ọgbẹni A, Oguntuga igba keji alaga A, Arowo- rade akọwe, C, Olu!e igbakeji aọkwe Ọgbẹni A O George Akapo L A Ajeniya akọwe eto owo, Ọgbẹ i W Jawando akọwe eto Ariya.

Awọn ọmọ ẹgbẹ nasi tun yan awọn enia mejila kan ti yio tun pẹlu awọn oloye na ninu wọn ni Ọgbẹni A A Aro- worade. Iya afin Kuburat Ogidan, Ọgbẹ ni L. O Durosemeti Ọgbẹni Bọrọkini A. O Abass, Iya afin A. Jombo A- A Bamgbelu L- Olu Ismel A A Kọya, Kay de Paul E O Ferera at, Iya afin akapo

Awọn ọmọ ẹgbẹ na tun ṣọ fun awọn oloye na lati se iṣẹ wọn pẹlu Ifẹ lati le bori ninu idibo ti nbọ yi

## Awọn Enia Naijiria O Dibo L'osu Kẹwa Ọdun Yi

# ILE IGBIMỌ AṢOFIN APAPỌ FẸ ṢE IPADE

Gẹgẹbi Irohin to de ọwọ wa labẹlẹ latiile iṣẹ Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria fi ye wa pe Idibo si ile igbimọ Aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria yio waye ninu oṣu kẹwa ọdun yi, Irohin na tun fi ye wa labẹlẹ lati ilẹ iṣẹ awọn igbimọ eto Ibo didi tun fi ye pe ninu oṣu kẹwa ọdun yi ni wọn yio dibo si ile gbimọ Asofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria.

Irohin wa tun fi ye wa yio ṣe ipade ikẹhin ti nwọn siwaju sii pe ile Igbimọ yio ṣe ki nwọn to tu ile Asofin ti apapọ Ilẹ Naijiria igbimọ na ka. Irohin si fi ye wa pe lẹsẹkẹsẹ ti Ile Igbimọ Asorin ti apapọ Ijọba na ba ti ṣe ipade Ikẹhin na tan ni Alakoso Ijọba apapọ ilẹ Naijiria Ọlọla Alhaji Abubakar yio sọ fun Arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Nnamdi Azikiwe pe ki o lo Aṣẹ rẹ lati tu ile igbimọ asofin ti apapọ Ijọba na ka latile lọ mura silẹ funawọn ẹgbẹ Oṣelu Jake - jado ilẹ Naijiria fun Idibo titun ti yio waye larin oṣu kẹwa ọdun yi.

Irohin na tun fi ye wa pe Ijọba apapọ ilẹ Naijiria si ti sọ fun awọn igbimọ ti nṣe eto lori ibo didi lati lọ mura gidigidi ki nwọn le tete pari iṣẹ to wa lọwọ wọn lati ṣe eyiti to jẹ pe o jẹmọ eto idibo ti nwọn yio di laipẹ yi ati pe ki awọn igbimọ eto ibo na tete mu-

Wo Oju Ewe Kẹfa

## Okotiẹ-Eboh Fẹ Da Ẹgbẹ Titun Miran Silẹ

EKO:- Alakoṣo eto owo fun apapọ Ijọba ilẹ Nijiria oloye Festns Okotie-Eboh ni Irohin fiye wape o ngbero lati da ẹgbẹ titun mira silẹ ni ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Nijiria ti ẹgbẹ Alakukọ nẹ kuna lati ba awọn ẹgbẹ Olomi N P C tiwọn ti ba papọ nṣe Ijọba tẹlẹ ti wọn ko ba papọ mọpe on ni lati da ẹgbẹ titun miran silẹ ni ipinlẹ Agbedemeji Iwọ Orun Naijiria,

Irohin na tun fi yẹ wa pe ẹgbẹ titun ti oloye Festus Okotie-Eboh yio da silẹ lerin oṣu yi ni a tun gbọ labẹle pe ẹgbẹ titun na pe on ylo papọ ọmọ ẹgbẹ Olomi N. P. C. gẹgẹbi awọn ẹgbẹ kan sẹ papọ ọmọ ẹgbẹ N.- P. C, Ninu awọn ẹgbẹ to papọ mọ ẹgbẹ Olomi ni ẹgbẹ Dẹmọ N. N. D. P eyiti olotu in n'ẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye Akintọla jẹ Olori ẹgbẹ na



Oloye OKOTIE-EBOH

Nigbati oniwe irohin wa lo ba oloye Okotie Eboh lati wadi nipa ẹgbẹ titun na lọwọ rẹ Oloye Okotie-Eboh fi ye oniwe irohin wa pe ọmọ ẹgbẹ N. C. N. C. lo on iṣẹ lati iberi ile opin,

Oloye Festus Okotie-Eboh tun sẹ alape fun oniwe irohin wa pe gbogbo nkan ti nwọn nro nipa on pe ki iṣẹ otitọ ni gbogbo ọrọ nu oloye Okotie Eboh tun sẹ alaye pe ti on ba fẹ da ẹgbẹ ti on silẹ pe on ni lati pe awon oniwe irohin sibi eto ipade ati pe ki iṣẹ ikọkọ ni on yio ti da a ṣilẹ.

## Awọn Oṣiṣẹ Da Isẹ Silẹ

IKẸJA :- Ni ọjọ 'Bo ti ise ọjọ kẹfa osu yi ni Irohin de ọwọ wa lati awọn ile Isẹ kan ni Ikẹja lẹba Eko pe awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ mẹrin kan to tobi julọ ni Ikẹja ati agbegbe rẹ tu da iṣẹ silẹ Irohin na tun fi ye wa pe Igbati awọn oṣiṣẹ nati da iṣẹ silẹ ti wọn ii taku mọ awọn alakoṣo awọn ile iṣẹ lọwọn tito nkan bi ọsẹ kan ṣẹhin bay.

Oniwe Irohin wa to lọ lati lọ ṣe Abẹwo si awọn ile iṣẹ ti awọn oṣiṣẹ ti da Iṣẹ silẹ fi ye wa pe Ariwo awọn Ẹrọ to ma nṣiṣẹ ninu awọn ile iṣe ti ki jẹ ki awọn enia gbọ nkan ti nwọn ba nsọ ti dakẹ jẹjẹ lai ṣiṣẹ mọ.

Oniwe Irohin wa tun ṣe Alaye pe awọn Oṣiṣẹ awọn ile iṣẹ to da iṣẹ silẹ na ko wo ẹhin lati wo ọhun ti yio ṣẹlẹ lori iṣẹ ti wọn da silẹ na ati pe ọpọlọpọ moto awọn Ọlọpa lo si ti ko awọn Ọlọpa kakun awọn ile iṣẹ na. Ṣngbọn awọn ọṣiṣẹ ko wo awọn ọlọpa na gbogbo awọn oṣiṣẹ lo si duro laiṣe iṣẹ kankan rara. Awọn ọlọpa kan pe Ijà ko ṣẹlẹ rara ni ile iṣẹ na

Gbogbo awọn oṣiṣẹ na lo duro kakari ọgba ile iṣẹ Merin na ti nwọn si ba ara wọn nsọrọ. Ṣugbọn ohun to jẹ pataki ti awọn oṣiṣẹ to da iṣẹ silẹ na nsọ ni pe nipa ekunwo owo-osu eyiti igbimọ Oluwadi Morgan se ti awọn Alakoso ile iṣẹ na kuna lati san fun awọn oṣiṣẹ, ti o si mu ki awọn oṣiṣẹ taku pe awọn ko ni se iṣẹ kankan laijẹ pe awọn gba ẹkunwo owo osu na gẹgẹ awọn Alakoso ile iṣẹ miran ti se san fun awọn oṣiṣẹ wọn.

ILE – ISẸ

Ninu awọn ile iṣẹ ti awọn oṣiṣẹ wọn taku pe awọn ko ni ṣiṣẹ ni awọn ile iṣẹ amọnyin Dunlop Nigeria Industry Limited, The Tower Aluminium Factory, The Clay Industry ati ile iṣẹ Funiture Factory.

Awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ mẹrin ti nwọn da iṣẹ silẹ na to ẹgbẹwa enia.

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Keje)

## Lati Ọwọ J. O. Shoyinka

Ogiriwo dahun: Idahun kini:- Mdi ọmọ ọgbọn ọdun nisisiyi. Idahun Keji:- Nda o Idahun Kẹta Ayunọrunbọ ni mo ba de ihin Onibode gba iwe ẹri rẹ o bọ ẹwu ọrun rẹ, osi fi aṣọ ala wọ ọ, oni ọjọ rẹ ko iti pe ki oto yọ si ọrun ganran lojiji, ngo daọ pada si ile aiye ki o lọ lo ọdun ti o ku si iwọ yio gbe adọrin ọjọ nihin ki oto le pada si ile aiye

AYUNỌRUNBỌ YỌ SI GANRAN

Nigbati o fiju kan Ayunọrunbọ o so mọ gbag oni moyo ko si wahala nihin ebi kosi nihin orugbo kosi aisan ko si atọsan atoru bakanna ni tile mi ki nmu ọ de ibiti ẹlẹda ti nsi ṣe iyanu.

Ile iṣe mokandinlogun lo wa nibẹ ile iṣẹ kọkan si tobi pupọ.

ILE IṢẸ KINI TI WỌN KỌKỌ WỌ

Ayunọrunbọ ṣaju Ogiriwo tẹle e Ayunọrunbọ fi han Ọga Ile iṣẹ Oju, o si gba tọwọ tẹsẹ ninu ile iṣẹ oju orişirişi ni wọn nṣe nibẹ omiran ri gbdogba omiran ri fitinfiti omiran ri sando omiran gbungbunrun omiran dabiri, ọpọlọpọ wa ni iwọntuwọnsi bayi ni awọn Maleka tonsa nṣe oju yi wọn rekọja si ibiti wọn ti nṣe agbari ina nla hẹ hẹ hẹ lowa nibẹ oju ti awọn amọkoko lọ iṣẹ ni awọn oṣiṣẹ ibẹ nlagun yọbọyọbọ olukuluku bẹrẹsi ṣe ori, ori rigidi omiran panb omiran gbọrọ omiran dorogi omiran ẹwẹ si pọgun lorişirişi ninu awọn ori wọnyi Ogiriwo woran titi o su patapata o sọ fun Ayunọrunbọ o ni eyiti ari yi tito Jọwọ jẹki alọ foju kan ẹlẹda Ayunọrunbọ ni ao iti de ibi kan Aṣẹṣẹ bẹrẹ ni o

AYUNỌRUNBỌ MU OGIRIWO WỌLE IṢẸ ETI

Nigbati nwọn wọ ibi ti awọn Maleka ti nṣe eti, inu ya Ogiriwo to bẹ gẹẹ ti tọkan lẹnu rẹ nitoripe eti miran fe bi eti Erin omiran ri konko omiran si na ṣanṣan ṣan bi eti ehoro ni kukuru wọn ṣe gbogbo bi ti awọn Maleka ti nṣe orişirişi ẹya ara wọnyi Ayunọrunbọ ni kekere lori yen ẹṣi ku ilu kan ti ao rekọja si ni bẹ ni awọn Maleka.




ti nto awọn ẹya ara wọnyi pọ ko si ọna lati gba wọ ilu yi afi iho ile Ọkan Ogiriwo nsọ kikiki onro ninu ara rẹ pe njẹ nṣe kọni Ayunọrunbọ fẹ lọ ti on si ọgbọn aini reti.

Ni kukuru Ayunọrunbọ fi ọpa ọwọ rẹ lulẹ kiki, ilẹkun aja ilẹ na si hoo,iṣẹju aya nwọn ti wọle, ẹnikan ko mọ ekeji mọ nibẹ, Olukuluku nsiṣẹ lọ ki ta Lọkunrin ati lobinri ni awọn Mọleka nmọ wọn jo, omiran kuru, omiran ri gbọnita, atari omiran rii jankanjankan, ete omiran dabi ti Rakunmi, ni kukuru orisirisi ni awọn Mọleka nda wọn-Ogiriwo woran titi oju rẹ ngbọn pẹrẹpẹrẹ Ayunọrunbọ wa pe Ogiriwo o ni nisisiyi ki awa to nlọ siwaju ẹlẹda Ọrun a t i aiye, nibẹ ni awọn ti ọmọ jọ yi yio ti gba ẹemi (ẹmi) ni bẹ na ni bẹ na si ni nwọn o ti ya chun ti nwọn y i o ṣe nile aiye, nwọni iwọ papa yio parada nibẹ l ti gba ile aiye lọ. Ọjọ keje gbako ni agba nibẹ, iwọ papa o yio şi tun ipin rẹ yan pẹlu

Ng'o ma pada lọ nisisiyi ti o badi ọjọ marun loni, ng'o pada wa ba ọ. Ogiriwo joko lẹnu ọna, o nwoye Awọn ọrẹ Ogiriwo tẹle Eṣu Gẹgẹbi mo ti sọ tẹlẹ ri, Eṣu ti tan awọn ọrẹ Ogiriwo jẹ, o si ti gba iwe ẹri. Nwọn ko mọ isoro kan rara, nṣe ni nwọn njẹ ti nwọu nmu, ti nwọn si nfi igbadun ṣe aya yala larin awọn obinrin ti o ti mu obinrin wa.

Nwọn nlọ rẹrẹrẹ, ṣugbọn eṣu ko sọ ibi ti o nko wọn lọ, nigbati o ṣe ni nwọn bere lọwọ rẹ pe ọjọ wo ni a o togunlẹ si ibiti a nlọ? Eṣu rẹrin musẹ, oni ẹma kalọ Eṣu bere lọwọ wọn oni njẹ ẹnyin ha mọ ẹniti emi iṣe bi? Nwọn ni rarao, oni ẹ fara balẹ ẹ o mọ mi nisisiyi ki ani eşu po ora ọnọ wọn loju yiyo ti yio yọ si wọn, o rekọja firi ni owa aṣọ alarabara pupa ati dudu ọkan ninu wọn ninjẹ ẹri ọkunrin towọ aṣọ alarabara pupa ati didu ọkan ninu wọn ni njẹ ẹri ọkunrin towọ aṣọ dudu kọja ni? E keji dahun pe lotitọ ọkunrin lo kọja ṣugbọn aṣọ pupa ni o wọ Eṣu da ede-aiye de sarin wọn Ija de nwọn bẹrẹ si lu ara nwọn wọn fẹ rẹ lu ara wọn pa, ki ẹsu to wa yọ si nwọn osi la wọn ni ija mo se ileripe ngo bẹrẹ itan nibiti Eṣu ti ba wọn de ilu Ẹeko Ọlọrun,

ESU BẸRẸSI SỌ ỌRỌ

Mo ki gbogbo nyin ẹku irọlu ẹku wahala ẹku ifọriti ẹniti oba wa kan ti o dan ko ni kọ oya ajẹkara Ọpọlọpọ nyin ko mọ mi ri lọjọ ki ni ti mo sọ pe ki ẹ tẹ e mi ẹ ko adi iru en a ti mo je laibikita ẹ tẹ'e mi Ninu gbogbo awọn Maleka Ọlọrun tẹlẹtẹlẹ ri e i ti ini akọkọ ṣugbọn ija wa larin emi ni ẹni akọkọ su Ọlọrun oja bo gbu olin rẹ ni mo si lodi si patapata ẹni ti oba si tẹ le mi yio bami pin inu iyami ti Ọlọrun iwa mi su emi papa emi ni mo nda ede aiyede silẹ larin ọmọ ẹda ogun ati ọtẹ emi ni mo wa nibẹ

Emi ni ma nsun ẹni rere jale, ma si ma ya olufọkan sin kuro li ọna ti Ọlọrun, eyi mu ki awọn ẹda bẹru mi, laifojukan mi nwọn a ma bẹru mi, nwọn a si ma gbadura ki nwọn ma ba ri ija mi.

O ni ẹ bere ohun ti ẹ ba fẹ lọwọ mi ngo si ṣe fun nyin, nitoripe owo tabua ọdọ mi lo wa nko le tan nyin jẹ rara ọrun apadi ni ẹ nlọ ẹ tẹlẹ mi awọn Ọrẹ Ayunọrunbọ bẹrẹsi wo ara wọn loju nwọn nwa riri wọn nfi ehin lu ehin ke-ke ke, ẹru ba wọn nigbati nwọn wa mọ daju pe eşu ni wọn tẹlẹ nwọn npa rida rida. Eṣu tun kigbe le wọn lori pe ẹ tẹ le mi, oju rẹ ti yipada li agbari o pọn fo o. bi ẹrẹ ẹyin kiamọsa nwọn ti tẹlẹ

Lagbara Oluwa ni owurọ ọla ẹ o ma ka iyoku lọ.

## Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ipade gbogbo gbo o yio wa fun awọn ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye ni ọjọ kẹsan oṣu kẹjọ ọdun yi (9/8/64) ni deede agogo meji ọsan ni nọmba 16, Bamgbose Street Lagos.

Atete de ṣe pataki

LATEEF BABALỌLA
Akọwe Agba

# IWE SI OLOTU

## Imọran Fun Ọmọ Ilu Omupo

Yio jẹ didun inu mi ki ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ lati ba awọn ọmọ ilu Omupo sọ ọrọ atata ati eyi ti ndun mi lọkan, asiko to fun wa lati wa idagbasoke ilu wa gẹgẹbi awọn orilẹ ede toku ti nwa ilọsiwaju ilu rẹ,

Pataki ọrọ mi si awọn ọmọ ilu Omupo ni pe ki nwọn je ki a ronu wa wo lori inawo tia nna papa fun awon o ilu nigbati ojẹ pe a ngira tabi wahala nla ni a nse kia to mọ ri tọrọ kọbọ ti a nri.

Ti aba si ri owo na tan. ti aba nse inawo kan; kaka ki a se bi a ti mọ rara o, odi ki a mọ kọja aye wa, ki a mọ na sile marun fun onilu ni ẹkan sọṣọ, elomiran nfi ele se fuja, nigbati talaka ba tun nfun olowo ni owo, ẹ ori wipe asise nla ni a se

Ki ba dara ti a ba kuku da owo na jọ bi ni ososu tabi ni ọdọdun bo ba pe titi owo na yio pọ to lati da isẹ silẹ ni ilu wa.

Gbogbo wa mọ wipe isẹ agbe ni a nse bi ilẹ ba ti mọ olukaluku yio gba ọna oko rẹ lọ tabi oko aru rẹ lọ kaka ki a fi owo ọbẹ silẹ iyawo wa nile ao ni se iyẹn a fi se ki a ri mi.

Ẹ jẹki a jawọ ninu pe a nna pọun kan sile mẹwa ati sile marun, ẹjẹ ki a tọju ile wa o emi alakiyesi ni o nba nyin sọrọ atata.

Emi ni
Alakiyeṣi Omupo.

ninu aiye yi,

Olotu mi ọwọn julọ Ọlọrun koni na arun karun sinn Ilu olukuluku wa ati ẹyin onikawe wa na Amin Ọgbẹni na si ọrọ sọ nio. Ki ẹyin agbagba forijin o

Emi ni Aburo yin,
Young Adebayọ Ilọrin

## Irohin Imọlẹ ku orire

Inu mi yio dun pupọ bi Olotu Irohin Imọlẹ balẹ gbani laya ati ki Iwe na ku ewu Ọdun kan ti Iwe na ti wọn da silẹ gbogbo awa ara Ibadan ni agbadun Iwe na pupọ

Ṣugbọn awọn agba ama ni Owe pe gele odun bi ki amọ we, Inu wa yio dun pupọ bi ẹba le ṣe eto bi Iwe na yio se kari gbogbo Ipinlẹ Iwọ-Orun Karọ Ojire nitoripe gbogbo awọn enia kakiri Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria ni onifẹ si Iwe na lọpọlọpọ to bẹ gẹ ti wọn fi ma sare ra iwe na tan kiakia ti wọn bati ri iwe na

Mo fẹ ki ẹba mi ki gbogbo awọn ti o nṣiṣẹ ni ile iṣẹ Irohin na pe wọn ku aforiti ati wahala mo si ki Iwọ Olotu papa Iwajuni ọpa ẹbiti yin yio ma mr rẹ sio

Emi ni
Abinbọla Akani
IBADAN.

## Ọrọ Lori Ilu Omu-Aran

Olotu mi totọ, Inu mi ibadun bi ẹba le gbami laye lati kọ Iwe ẹsẹ lines meji yi sinu iwe oloyinmọmọ yin lati fisi si ọrọ kan tojade ninu iwe Irohin Imọlẹ ti ọjọ Aje 13/7]64 ti Ọgbẹni kan ti operukọ ararẹ ni JIMOH AROWOSAFẸ kọ ti osọ sinu iwe na pe Arun pọju ninu Ilu Omu - Aran ibadura ki ọgbẹni na tilẹ sọ iru arun topọ ninu Ilu na yala Warapa ni Asiwin tabi Ẹtẹ - Leprosy.

Bi oba jẹpe ẹpọlọ Ọgbẹni na kodaru ti aba sijẹ pe ọmọ bibi ilu Omu - Aran ni ọgbẹni na ajẹ wipe agbole tiwọn nikan ni Arun pọsi kise gbogbo Ilu Omu Aran nitori ni agbole tiwa ni Ilu Omu - Aran wọn o pitan rẹ fun mi ri: pe arun kan ma nse wọn ni Ilu Omu - Aran ju ori fifọ lọ bẹni kosi ẹniti ori kifọ

## Ilu Omupo Nfẹ Atunse

Olotu jọwọ gbami ni aye diẹ ranpẹ ninu Iwe rẹ Olo inmọmo ki Oluwa ma jẹki ọwọ nyin roke mo ki Olotu pe wọn tun ku ajọdun Irohin Imọlẹ Oluwa a jẹ ki ari ọjọ ọdun;

Mo kesi Olotu Ipinlẹ Ariwa Ọlọla Amọdu Bello ki o lo ipo rẹ rere lati ba wa tun omi ẹrọ ilu wa ṣe ati lati tete tunṣọna ilu wa ṣe pẹlu,

Inu wa yio dun bi Olotu wa ba le tete da wa lohun nitoripe awọn ara ilu Omupo ki ifi owo ori jafara rara.

Mo dupẹ o Olotu

Emi ni
Emmanuel Rocky Boy
OMUPO

PHILIPS
for
RADIO
PHILIPS

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIKI



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo ara Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọgbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin gbogbo.

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala ṣiṣẹṣẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'ido dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" n gbakugba yio salọ pẹlu igoaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patroise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Printing Press**

**16 Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos

# Alakoso Irohin Imọlẹ Dupẹ Fun Ọlọrun

OLOTU:- Bi aba kani si, ti asi ṣe ni ni oore, ọpẹ ni a du Alakoso Irohin Imọlẹ mọ oore, O si dupẹ fun Ọlọrun, Iwa ọmọ Luwabi ni eyi.

Ni ọjọ Ọjọ'Bọ ti iṣe ọgbọn ọjọ oṣu keje odun yi, ni ọjọ na ti Irohin Imọlẹ pe ọduu kan tio ti njade lojojumọ, alakoso iwe gbajumọ na dabira, o pa ẹran a bọra o si se ase rẹpẹtẹ titi di ọjọ keji, ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kọkanlelọgbọn ọti ati "7up" poju, ko ni iye. Nitoripe mo jẹ ọkan ninu wọn o orire ọjọ na ti o si mu "7 up", daada Tẹrun - tẹrun mo dupẹ pupọ lọwọ Alakoso Irohin Imọlẹ ati Olotu ati awọn yoku ti o tọ si lati dupẹ fun Aseyijamọdun o.

Alhadji Awaiyewaṣere Eko

## Hadji Imam Rahim Jalaisi

Ni ọjọ ru ti iṣe ọgbọn ọjọ oṣu keji ọdun yi ni Alhaji Imam Abudu Rahim Aiyepe lọ jẹpe Ọlọrun ni igbati odi ẹni ọdun merindilogọta si ile rẹ 27) Church street, Eko lẹhinti oto se ailera fun ọjọ diẹ.

Ni ọjọ keji ti ose jalaisi ni awọn Lemọmu, awọn Alhaji, awọn alfa ati awọn sanmari musulumi si gbe oku rẹ lọ sin ni Ilẹ- Oku Oke sina Hadiji- Imam Agba mọsalasi alalukuran si ni ose isin fun un.

Awọn Alhaji Ọmọ Ọba A' W. Elias Hadiji Y. A.Disu Hadiji Imam Is aka Shittu Hadji Akanbi Bursimoh' ati awọn Hadji Ọmọ-ọba Danialu Adejimi Akitoye ati awọn Ọgbẹni Lamidi Sadiku, L midi Apatira' Abudu Liadi Y. Eletu ati R. Eletn pẹlu awọn bi igba enia ti o lọ ba wọn ṣe ẹyẹ isinku na.

Ni igba aiye rẹ, musulumi ododo ti o si fẹ ise fun awọn enia ni ologbe na jẹ.

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 21-Feb 18) O jẹ ohun ti o lẹwa pupọ bi iwọ ko ba ṣe awọn eto ti o ti ma nṣe ninu ile telẹtẹlẹ nitoripe awọn enia buruku le da ijọgbọn silẹ ninu ile rẹ

PISCES (Feb 19–Mar 20) Isoro kan yio bẹ sinu ọrọ ara rẹ suru ni ki o fi gba mẹṣe ṣe ni ọrọ pajawiri

ARIES (Mar 21-April 20) Ṣọra fun ọrọ ijo kekere kan ti o fọ be sile ninu ile rẹ, ṣe pelẹpelẹ ọgbọn ati ẹlẹ ni ki o fi yanju rẹ

LEO July 23 - Aug 22:- Ibinu ko da nkan suru ni baba iwa o si le ba iṣe rẹ jẹ, bi o ba kuku joko kio fi ọwọ leran mawo ha sun mọ wọn tọ.

VIRGO Aug 23 Sept23:- Bi o ba le ṣe suru ohun gbogbo yio juse fun ọ nṣe ni ko o tunbọ mura si gbajumọ rẹ.

LABRA Sept 24- Oct 23:- Iwọ yio gba dajudaju pe ọtọ ni ọjọ oni yi jẹ fun ọ ninu gbogbo ọjọ ti o ti mba pade Ọgbọn ori rẹ, ati ẹ'ẹda rẹ yio ran ọ lọwọ ti iwọ yio si fi bori awọn iṣoro gbogbo ti o wa yi ọ ka.

TAURUS (April 21 - May 22) Ire ojiji kan ti o ti fi ẹnu atẹ kan wipe bi enia ba nta iru ayo bawọnni nṣe ni aluwarẹ nfi owo rẹ sofo danu, iwọ o jẹ ayo na, aṣalẹ ọjọ na yio rọgbọ fun ọ.

GEMINI (May 23 - June 21) Iwọ yio jẹ ere kan lo ni lati ọdọ ọkan ninu awọn ọrẹ rẹ, dide ki o si gbadun ara rẹ.

CANCER (June 22 - July 22) Ọgbọn ori lasan ni yio ro ti ara rẹ nipa ọrọ iṣe ko ṣe iṣe kan, bi o ba ṣe ṣe, maṣe lọ sibi ase kan ti nwọn gbe pe ọ lalẹ oni.

SCORPIO(Oct54–Nov22) :Ọrẹ rẹ kan yio wa pe ọ lati jijọ lọ si ode ni alẹ oni ode na yio si miringindin fun ẹnyin mejeji.

SAGITTARIUS (Nov23-Dec21)-:Itẹlọrun ni gbogbo ọjọ oni yio jẹ fun ọ li aṣalẹ ui iwọ o to awọn ohun ti o fẹ ṣe,

CAPRICORN (Dec22-Jan)-:Ori rẹ ati ero ti o nba li okan rẹ iie ni yio jasi awọn enia yio si ma fi ọ se yẹyẹ.

HELLO ! HELLO !! HELLO !!!

**OLUSHI SOCIALISTS**

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

**at Foresters Centenary Hall**

22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p. m. till dawn

*MUSIC BY*

**New Time Enterprises Bashy & His Young Stars Orchestra**

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

**Bar Bar Inexhaustible**

**Tickets 3s Flat**

Tickets obtainable at 16, Bamgbose Street Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos.

MAFI OWO RẸ ṢE "OFO" MỌ NIPA RIRA AWỌN KỌBIPỌBI TỌNIKI NITORIPE AWỌ WỌN ROJU ARA RẸ I O NSE IYẸN DAJU O BẸRẸ OJOLO KO HAUNHAUN AYỌNRAN TỌNIKI TI WỌN NPE NI

# "MINOPHOS–TONIKI'

Aworan ẹgbẹ yi fi han ọ gbangba bi ẹda eni ti ri laisi "ẸRAN ARA" atipe ojulowo toniki to le ṣe iṣẹ ribiribi ni ẹjẹ ara, iṣọri ara ninu egungun geẹgbi awọran yi to fi han ọ, MINOPHOS Toniki a ma ẹjẹ fa ti tun si ara, papa t e ia ba nru si ogurodo tabi fun wahala iṣẹ ṣiṣe aiko ori orun sun daradara to, beni o si darajulọ pelu bi ara enia ba ngbẹna nigba' ngba tabi lehin aisan tabi amodi bi igbona, ib pọ junọnju tabi a a wiwo enia nigbakugba,




At fun iṣọn a lokun ati egungun ara ti o ba dabi enipe omurọ tabi ti ko la gbara to. Ṣi d n igo kan egbogi toniki vi wo wọ yio si ma rohin rẹ fun gbogbo enia pẹlu. Bere ni Ṣọbu awọn:-

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

WATERLOO CH P MEDICINE STORES
8, P LMCHURCH STREET LAGOS
P, O, BOX 333

# Agbọrandun

Lati Ọwọ ỌMỌTAYỌ

Mo ki yin gbogbo ẹnyin onkawe Irohin Imọlẹ l'ọmọde ati agbalagba loko ati lodo aranse Ọlọrun yio ma ba gbogbo wa nibikibi ti a ba gbe wa.

O ti pẹ ti mo ti nwa aye lọdọ Olutu iwe Irohin Imọlẹ lati le ma fi iriri mi han si gbogbo agbaiye ni orişirişi ohun gbogbo ti mo nri ti o si nşẹlẹ kakiri lode oni, şugbọn inu mi wa dun lọpọlọpọ wipe olotu ati alakoso rẹ gba mi ni aye na fun ilosiwaju ilẹ wa Naijiria to kun fun wara ati oyin.

Ki nto bẹrẹ isẹ mi gẹgebi ati gba mi ni aye mo rope o to si o tun yẹ lati dupẹ gidig di lọdọ alakoso iwe Irohin Imọlẹ na, nitoripe gele ko dun bi ki a mọ we, kamọwe ko to ko yẹni rigbati mo ri alakoso iwe na emi ko kasi rara şugbọn mo yin Ọlọrun ọga ogo ninu ọla nla rẹ fun ọgbọn imọ ati fun arakunrin na lati lẹ gbe isẹ iwe Irohin k lẹ laisi imọ ẹgbẹ oşelu tabi owo yiyi lọdọ Ijọba, Adura mi ni pe ki Oluwa kio ran alakoso na lọwọ ki ọwọ rẹ tu bọ ma roke.

KILO NFA OLE JIJA AWỌN ỌDỌ

Lati ọjọ ti mo ti nri orişirişi iwa ai tọ ati ai yẹ ti o ndi ẹwu fun wa lode oni ni o ti nwun mi lati mọ ba ara wa sọrọ boya bi a ba nfi ọrọ jomitorọ ọrọ irufẹ iwa ibajẹ ba wọnyi yio ma dinku diẹdiẹ.

Ti ẹnikẹni ba sọ pe ohun ko mọ ohun ti o nfa ole jija iro funfun ni a o ba ndi rẹ. Ẹnikẹni ti o ba ni oju ki koro mọ pe ki a tẹ oju mọ ohunkohun tabi ki a sọrọ ki a ma mu ẹnu kuro nibẹ iru ifẹ bẹ iwa meji yi ni o nmu ole jija wa, nitoto Ọlọrun ti daa mọ şugbọn ko kọ wa pe ki a ma fi jale o kọ wa ti a ba ri ohun ti o dara ki a wo ni awofin ki asi fi sọkan ni sişe nipa iranlọwọ Oluwa pẹlu igbẹkẹle lori işẹ rere ọwọ wa

Şugbọn dipo ki a şe eyi ere bawo ni a o ti sare şe ohun ti ẹnisaju ti sẹ boya ọdun mẹwa tabi jubẹ lọ lo fifi ebi pa ara rẹ ki o to se ohun ti o gbe kalẹ Ọdọ iwoyi fẹ se larin oşu mẹta, bawo irufẹ asiri bayi ko şe ni tu.

Nigbati o jẹ wipe lati ọjọ ti ot, rii ri o ti nro eyiti yio şe ni bi sẹ. boya yi yi iwe ni tabi yio ro kọ ọrọ ile owo, irufẹ eyi ni on mu asi ri ẹlomiran tu ti yio ma sọ nile rẹ pe awọn ti ko fẹran oun ni oşe oun, sugbọn nigbati onse ti gbogbo rẹ udun ko ri ẹni ti ose.

Nitori idi eyi mo bẹ gbogbo ẹyin onkawe Irohin ti ẹ nka iriri mi lati oni wipe ki ẹ lẹki an suru pẹlu ohunkohun ti Ọlọrun şe fun ẹnikọkan wa nitori eyi ni ajẹmọnu ti ẹnikẹni kọle şi yemeji si wa ti ao si ma rin ti ao ma yan

Ni igbamiran ti Ọlọrun ba da ẹmi si emi yio sọ irisi mi nipe awọn Ọdọmọbinrin wa paapa awọn ọmọ ile wa.

---

# PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu ni akan bi o dun kan tabi ju ẹ lo awọn egbogi rọ irọbi o le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, lu Faranse ti wọn up ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun In otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, I ọ iil , Ikọ ti o mu mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs) tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba an 1go kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iya tọ ninu ara rẹ ui kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i Łsb gi Ikọ miran ni Şọbu awọn:—

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọja Ita Faji) .......
Adedun Chemist
14, Weakman Street, Yaba

# UROLYSN DRAGES'

Fun Itọju tabi fifọ Apo Ile Itọ (Kidney-Bladder) fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ ti ẹnu. ẹhin didun Ibadi Gige tabi riro, eri ile itọ a tabi tlọ-jijo eniaitọ riruo, rukuruku sẹ,ọn, aikoleri itọ lati ọ to, lakuregbe, orunkun ọwọ, ẹ. Ejika wiwu tabi riro



Ara sisan. titobiju aikole gbe ara kọnkọn tabi kiakia didaju loru nigbakugba, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi, ba wọn. yi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹko si ni ilu Naijiria nitorina şọra ki awọn eleru tabi awọn ori rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ, maşe gba rara! Owo rẹ jẹ Sile mẹfa abọ 6/6d owo Ọkọ Sile kan abọ (1/6d)

Bere Egbogi yi ni şọbu awọn:-

NIGERIA MEDICINE STORES
4' TIUNBU SQUARE, LAGOS

---

# Awọn Ọja Ajẹbidan

Iwe ilana Ifa Iyanrin titẹ. Etutu şişe Iwosan ati egbog ajẹbidan ti o ba ni iwe yi lọwọ, abiku koni yọọ lẹnu mọ oso ati aje ko ni lagbara lori rẹ, owo paapa ko ni wọn ni ohunkohun toba si dawọ rẹle ni yio ja şi rere awọn baba awon ti o gbowo gba asọ lọwọ enia ko ni ri gba mọ Iye owo rẹ 20/-

Iwe egbogi ajẹbidan Agbalietu awọn Ogun Ajẹbidan ti o wa ninu iwe yi ko şe sọ a fi ti o ba raa, ti o ba ni iwe yi lọwọ şaşa arun ni o ko ni le wo ko si ni ijaiya pe arun tabi Amodi kan le pa ọ Iye owo 25/-

Turari Ẹyọ.u Ajẹ- ti o ba nfin turari yi ba a ti şe şure rẹ Ajẹ ati abatẹnijẹ ko ni foju si ọ lara ohun kohun ti o ba si dawọle rere ni yio maa ja si, iwọ ko ni mọ aita ọja agbana ko si ni wọ igba rẹ idabobo siwa fun iwọ ati awọn ẹbi rẹ.

| | |
|---|---|
| Pangolo kan | 10/6d |
| Kekere | 2/6d |
| Iwe Gbedegbẹyọ Hausa | 3/ |
| Itumọ Josẹfu Alala | 5/- |
| Itumọ Ami Ara | 3/- |
| Eewo ilẹ Yoruba ati Etutu | 4/6d |
| Afọşẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Ajẹbidan | 3/6 |
| ati agbara Psalm ẹgun lori awọn Ajẹ pẹlu Ara | 30/- |
| Tailos Measurement works | 2/- 6d |
| Iwe lori iyege Ikọşẹ (Certificate of Apprenticeship) ẹyọ kan | 5/- 12/- 6d mẹta |
| Iwe Adehun larin Onile ati mehaya Tenants (Agrement Form) | 10/- 6d mej |
| Iwe Aşofofo Alejo (Visitors not Book) | 2/-6d |
| Iwe Alagbafọ (Laundry Book) | 5/-6d |
| Kadi ifisọrọ sinu redio lọfẹ | 2d |
| Iwe Egbogi Ajẹbidan fun itaja ati Işegun Ajẹ | 16/- |

# APEJUWE ILE IŞẸ WA

Wọ Bọsi ti onlọ si Lawanson ni Yaba 3d pe bi, ti o ba sọkalẹ ni Lawanson, bere Ilu Itirẹ. Ti ba de Ilu Itirẹ bere ibiti nwọn ti npa malu, titi ti ile itawe wa wa. Ti o ba fẹ fi owo ranşẹ fun rira adirẹsi mi niyi:—

J. O. Shoyinka
c/o Postal Agent,
1, Isiba Street
Itirẹ Via,

